# KAINI ATI ABẸLI

### Gẹnẹsisi 4:3-16

### ẸKỌ 4 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ wá OLUWA nigbati ẹ le ri i" (Isaiah 55:6).**

**Ẹbi Kin-in-ni**

Nigba ti Adamu ati Efa di baba ati iya Kaini, ni igba kin-in-ni ti a kọ́ bi ọmọ-ọwọ́ sinu ayé. Iru ọlá wo ni Ọlọrun fi fun Efa – "iya alãye gbogbo" (Gẹnẹsisi 3:20). Lai pẹ ọmọkunrin keji ti wọn pe ni Abẹli mu inu ẹbi kin-in-ni yii dùn.

Nigba ti awọn ọmọkunrin meji wọnyii dagba to, lai si aniani Adamu kọ́ wọn lati ṣiṣẹ. Igbesi-ayé rẹ̀ jẹ eyi ti o kún fun iṣẹ -- oko wà lati ro; ẹgun on oṣuṣu wà lati kó kuro ninu oko; maluu ati agutan wà lati tọju. Abẹli ni o maa n mu awọn agutan lọ si pápá oko tutu, lọ si odo omi ti n ṣàn, ti o si maa n ṣọ́ wọn ki ẹranko buburu má ba pa wọn lara. Kaini n ṣiṣẹ ninu ọgbà ati ninu oko.

**Ẹbọ si Ọlọrun**

Bi o tilẹ jẹ pe a kò ti i fun ni ni Ofin, Ọlọrun gbọdọ ti sọ fun Adamu lati mú awọn akọbi ninu agbo ẹran rẹ̀ wá gẹgẹ bi ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ, nitori lẹyin naa Ọlọrun fi aṣẹ yii lelẹ ninu Ofin. Lai si aniani, Adamu ti kọ́ awọn ọmọ rẹ̀ ni ọna ti a le fi sin Ọlọrun pẹlu. Bẹẹ gẹgẹ ni lọjọ oni nigba ti awọn obi Onigbagbọ́ ba lọ si Ile-Ọlọrun, ti wọn gbadura, ti wọn si ka Bibeli, awọn ọmọ yoo kọ́ lati tẹle apẹẹrẹ wọn. Awọn ọmọ ti obi wọn kò naani lilọ si Ile-Ọlọrun, ti wọn kò si naani adura ati kika Ọrọ Ọlọrun, yoo tẹle apẹẹrẹ ti awọn obi ti wọn kò bikita ti wọn kò si ri igbala ba fi lelẹ pẹlu.

Ni ọjọ kan, Kaini ati Abẹli mú ẹbọ wá sọdọ Oluwa, ijẹwọ aini wọn fun ibukun Ọlọrun. Kaini ti ṣiṣẹ karakara ninu ọgbà rẹ̀, o si mu diẹ ninu eso rẹ̀ ati ewebẹ lati fi rubọ si Ọlọrun. Pẹlu eso ilẹ, ti i ṣe iyọrisi laalaa rẹ̀, o n wá ojurere Ọlọrun nipa iṣẹ́ rẹ̀. Abẹli mú ọ̀kan ninu awọn akọbi agutan tabi ewurẹ wá fun Oluwa. Boya o fi pẹlẹpẹlẹ wá inu agbo rẹ̀ ki o ba le ri ẹran ti o dara jù lọ. Boya o fi pẹlẹ bọ́ akọbi agutan tabi ewurẹ yii, ki o ba le jẹ́ "ẹbọ ti o san ju lọ" fun Ọlọrun.

Ohunkohun ti a ba fi fun Oluwa tabi ohunkohun ti a ba ṣe fun Un, gbọdọ jẹ eyi ti o dara jù lọ. Ẹ ma ṣe jẹ ki a fun Un ni ohun ti kò ná wa ni ohun kan lae, nitori ko si ibukun Oluwa lori iru ẹbọ bẹẹ.

Lẹyin naa, a ri i pe Ọlọrun fun awọn Ọmọ Israẹli ni ofin pe ẹbọ wọn gbọdọ jẹ́ ọdọ-agutan "ailabùku, akọ ọlọdún kan: ẹnyin o mú u ninu agutan, tabi ninu ewurẹ" (Ẹksodu 12:5). O le jẹ pe Ọlọrun sọrọ si ọkàn Abẹli, ti O si sọ fun un lati ri pe ẹbọ ti o mu wá jẹ ẹbọ pipé. Gbogbo eyi n tọka si ọjọ naa nigba ti Jesu, "Ọdọ-Agutan Ọlọrun" ti ko ni abawọn yoo fi ẹmi Rẹ̀ lelẹ gẹgẹ bi ẹbọ lori Agbelebu ni Kalfari ki a ba le ra ẹlẹṣẹ pada.

**Otitọ ati Eke**

Paapaa ni akoko yii gan an, a ri ẹsin meji -- ẹsin tootọ ninu eyi ti ẹjẹ etutu fun ẹ̀ṣẹ wà, ati ẹsin èké, ti ko naani ẹjẹ Jesu ti o si n wá idalare nipa iṣẹ ọwọ́ rẹ̀. Ẹbọ ta ni Ọlọrun gbà? Oluwa "si fi ojurere wò Abẹli ati ọrẹ rẹ̀; ṣugbọn Kaini ati ọrẹ rẹ̀ ni kò nãni." Ọlọrun wo ọkàn awọn eniyan meji wọnyii, gẹgẹ bi O ti n wo ọkàn awọn eniyan lonii pẹlu.

**Iyatọ**

Ọrọ Ọlọrun kọ́ ni gbangba pe "laisi itajẹsilẹ kò si idariji" (Heberu 9:22). A si tun ka a pe lai si igbagbọ́ kò ṣe iṣe lati wu Ọlọrun. Abẹli mu ẹbọ ti o ni tita ẹjẹ silẹ ninu wà, o si wá pẹlu igbagbọ́. Itumọ eyi ni pe o gbagbọ́ pe ọna Ọlọrun ni ọna ti o dara ju lọ ti o si tọna. Ṣugbọn ni ti Kaini a ka pe o "dide si Abẹli arakọnrin rẹ̀, o si lù u pa." "Nitori kili o si ṣe pa a? Nitoriti iṣẹ on jẹ buburu, ti arakọnrin rẹ̀ si jẹ ododo" (1 Johannu 3:12). Nihin a ri iyatọ laaarin Kaini ati Abẹli.

**Ajẹriku Kin-in-ni**

Abẹli ni ẹni kin-in-ni ti o kọ́ kú iku ajẹriku kin-in-ni nitori ẹsin, ṣugbọn o kú ni igbagbọ́; lati ọjọ naa wá, ọkẹ aimoye eniyan ti fi ẹmi wọn lelẹ nitori Ọlọrun ati otitọ.

**Ọkàn Buburu Kaini**

"Kaini si binu gidigidi, oju rẹ̀ si rẹ̀wẹsi." Iṣẹ ọkàn buburu, ati owu hàn ni oju rẹ̀; gẹgẹ bi ikúuku ti maa kojọ pọ si ibi kan ṣaaju iji, wọn jẹ ikilọ ohun buburu ti yoo tẹle e. Nigba ti ẹni kan ba ṣe ohun ti ko tọ́, loju kan naa ni yoo hàn loju rẹ̀; ṣugbọn nigba ti eniyan ba ṣe ohun ti o dara, oju rẹ yoo fi ayọ̀ hàn, yoo si tuju ka.

**Bibò Mọ́lẹ̀**

Lẹyin eyi, a kà pe Kaini purọ́ lati gbiyanju lati bo ipaniyan naa. Ẹni ti o ba daṣa lati dẹṣẹ yoo gbiyanju lati fi eke bo o mọlẹ. Ko si ẹ̀ṣẹ nla tabi kekere, ti Ọlọrun gboju fò dá. Ẹjẹ Abẹli ni ohun ti o kigbe soke, o si dé eti Ọlọrun Alagbara, ti O sọkalẹ wá, lati bá Kaini sọrọ nipa rẹ̀.

**Ijiya**

Ọlọrun sọrọ egun fun Kaini, O si sọ fun un pe dipo ki o maa gbé ni alaafia laaarin awọn ẹbi ati ará rẹ̀, isansa ati alarinkiri ni oun yoo si maa jẹ ni ayé, lọna to jin réré, lai si alabarò. Iru idalẹbi ti o ba ni lẹru wo ni o tẹle e bi o ti "jade lọ kuro niwaju OLUWA" o si lọ gbe ni ilẹ Nodi, eyi ti itumọ rẹ̀ n jẹ "alarinkiri" tẹlẹtẹlẹ. Lai pẹ gbogbo awọn iran ọmọ rẹ̀ ni o parun patapata eyi ti o fi hàn pe "ọ̀na awọn olurekọja ṣoro" (Owe 13:15).

**Ẹṣẹ ati Didagba Soke Rẹ̀**

Ọlọrun ti sọ fun Kaini pe, "Bi iwọ kò ba si ṣe rere, ẹ̀ṣẹ ba li ẹnu-ọ̀na." Ẹṣẹ ni o fa pupọ ninu wahala ti o wà ni igbesi-ayé eniyan. Yoo maa pọ̀ si i ni igbesi-aye ẹlẹṣẹ, bi ko ba si ronupiwada rẹ, yoo rán ọkàn rẹ̀ lọ sinu egbe ayeraye. Kaini kọ́ jowú; lẹyin naa o binu, o paniyan; o si tun purọ́. O ni ọkàn buburu, ojú buburu, ati ọwọ́ ikà. A ti fun un ni anfaani lati ronupiwada, ṣugbọn dipo eyi, o jẹ ki ikoro ati ikorira rẹ̀ pọ si i, ki o si tun jinlẹ si i si arakunrin oun tikara rẹ̀. Bibeli wi pe ẹnikẹni ti o ba "korira arakọnrin rẹ̀ apania ni" (1 Johannu 3:15), nihin ni a le ri aworan tootọ nipa eyi. Ẹṣẹ maa n dagba. Lojiji ni yoo bẹ́ jade gẹgẹ bi o ti ri gan an, pẹlu ipá ti o ba ni lẹru, pẹlu agbara ti o buru. Ko ti i si iwe ti a kọ ti o fi bi ẹ̀ṣẹ ti jẹ ohun ti o buru ju lọ hàn gbangba pẹlu agbara, gẹgẹ bi Bibeli ti ṣe. Nigba ti awọn obi Kaini, Adamu ati Efa, di alabapin ẹ̀ṣẹ, o dabi ẹran omi (octopus) ti o si ọwọ ija rẹ mẹjẹẹjọ de ori gbogbo iran ẹda ti n bọ̀ lẹyin.

**Kikiye-sara**

Ẹ jẹ ki gbogbo awọn ti o n ka itan Kaini ati Abẹli kiyesi ọna wọn, ki wọn si bẹru ki owú tabi ikorira diẹ má ba yọ wọ inu ọkàn wọn. Nigba ti o ba si ri bẹẹ, ko si bi o ti le kere tó, o le dagbasoke titi yoo fi bẹrẹ si jọba lori ẹni naa patapata; nigba naa bi kò ba ronupiwada rẹ, yoo mu ki oluwarẹ maa lọ jinlẹjinlẹ sinu rẹ̀, nikẹyin yoo rán oluwarẹ lọ si ọrun-apaadi lọdọ eṣu. Bawo ni o ti ṣe danin-danin to lati ni ọkàn ti o ṣe deedee!

## AWỌN IBEERE

1 Ọmọ ta ni Kaini ati Abẹli i ṣe?

2 Iru iṣẹ wo ni wọn n ṣe?

3 Ni ọ̀na wo ni Abẹli fi mu ẹbọ ti o sàn ju ti Kaini lọ wá fun Ọlọrun?

4 Ẹbọ ta ni inu Ọlọrun dùn si? Ki ni ṣe?

5 Ki ni eyi mu ba Kaini, ki ni o si ṣe?

6 Ki ni ijiya rẹ̀?

7 A mọ̀ Kaini gẹgẹ bi apaniyan kin-in-ni. Ki ni a mọ̀ Abẹli si?

8 Njẹ o le darukọ awọn miiran ti wọn fi ẹmi wọn lelẹ fun Ihinrere?